# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE. TẸNI GBOGBO LAWA

No. 592 WEDNESDAY APRIL, 29 1964 (2D)


## Nwọn Dana Sun Obinrin Kan Laaye !

ABAK:— Jinnijinni dabo gbogbo enia nigbati nwọn si ji ni kutukutu owurọ ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹdọgbọn oṣu yi ti nwọn si ba Iyawo-ile kan, Iyaafin Mba Udo, ẹni ọdun mejidinlọgbọn n nu oko kan ni Abak ni agbegbe Ikọt Ekpẹnẹ ti nwọn yin obinrin na lọrun si ẹhin, nwọn si tun dana sun un.

Irohin awọn Ọlọpa Kalaba fi ye wa pe lati bi ọjọ mẹta ni nwọn ti nwa obinrin na, nigbati awọn enia rẹ wa titi, ti nwọn ko si ri, ni awọn ba wa fi ọran na han awọn Ọlọpa ni Teṣan pe, awọn ti nwa obinrin na to ọjọ mẹta sẹhin nigbana.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn Ọlọpanu ba jade si arin ilu ti nwọn si fi ọgbalẹgbalẹ kakiri gbogbo ilu, gbogbo arin ilu, ile ahoro, ati kọrọ ni awọn Ọlọpa wa, ṣugbọn nwọn ko ri t'oku t'aaye obinrin na.

Ni ọjọ keji ni ọmọ obinrin na wa lọ si inu oko kan ni agbegbe na, nibiti o ti nwa iya rẹ laisimi, ni o ba ri oku iya rẹ ninu oko kan, ti awọn enia kan pa iya rẹ si.

Irohin fi ye wa pe, nwọn fi ipa ba obinrin na ja ija nla, nitori ijaṣẹ nla lo wa nilẹ ibẹ ki nwọn o to le yin ọrun obinrin na si ẹhin, nwọn pa, nigbati nwọn pa tan, nwọn si da ina si oku rẹ.

Awọn Ọlọpa ti gbe oku obinrin na lọ si Ile-iwosan lakulaku, nwọn si nwadi ọran na lọwọ.

### Ọdẹsanya Sọ pe:

# AWỌN ỌLỌPA HALẸ MỌ OMIṢADE PẸLU IBẸRU

EKO:- Gbogbo awọn ero ile ẹjọ lo la ẹnu silẹ ti nwọn ko si le pade mọ nigbati Ọgbẹni M. A. Ọdẹsanya, ọkan ninu awọn agbẹjọro ti o nse ẹjọ *Oloye Ọbafẹmi* Awolọwọ, olori ẹgbẹ Afẹmfẹre sọ niwaju ile ẹjọ lana pe, awọn ọlọpanu halẹ mọ Ọgbẹni M. A. Omisade pẹlu ibẹru lati gba ọrọ silẹ lẹnu Olujẹjọ na ni Teṣan awọn Ọlọpa nigbati nwọn muu.

Ọgbẹni Ọdẹsanya wa pe akiyesi Ijoko awọn Adajọ si ẹjọ ti nwọn kọ silẹ ninu iwe ti nwọn fi ro ẹjọ niwaju Adajọ Agba, Ọgbẹni G. S. Ṣowẹmimọ.

Ninu rẹ ni nwọn ti sọ pe, ki Omisade wo ilẹ ki owo oke, ki o si tun wo gbogbo awọn nkan ti o ba le ri, nitoripe ko tun ni ri wọn mọ, arimọ rẹ ni eyi yio si jẹ ti ko ba sọ "otitọ ọrọ" fun awọn, nitoripe awọn yio ti oju rẹ yẹ ibọn awọn o si ti ẹhin rẹ bọ ọ.



Oloye AWOLỌWỌ

ILE IWOSAN

Ọgbẹni Ọdẹsanya tun ṣe alaye pe, nigbati awọn Ọlọpa yọ ibọn jade ti Omiṣade ri ohun ti Ọdẹsanya pe ni "Ajagbemọni-ki-otopauri" ni o ba bẹrẹsi sọ gbogbo ẹjọ ti o ro fun awọn Ọlọpa ti nwọn si fi kọ awọn ẹjọ na silẹ.

Ọgbẹni Ọdẹsanya sọ pe, awọn Ọlọpa ti kọ fi Ofin pajawiri gbe Ọgbẹni Omisade tẹlẹ, ki o to di wipe ara rẹ ko ya.

Nigbati ara Omiṣade ko ya, Ọgbẹni Ọdẹsanya tun sọ siwaju, ni o ba fi lọ si Ile-iwosan ti nwọn npe ni "Greck Hospital" L'Eko, ninu ile iwosan na ni o wa lori akete aisan ti awọn Ọlọpa fi mu "iwe amunimada" lọ fun un, Ṣugbọn Omiṣade kọ lati gba iwe na nitoripe ara rẹ ko ya, ko si gbadun pẹlu.



Ọgbẹni OMIṢADE

ẸBẸ IKUNLẸ

Ọgbẹni Ọdẹsanya tun wa be akiyesi ijoko awọn adajọ si akọsilẹ ẹjọ ti awọn Ọlọpa ro niwaju adajọ, nibiti ọga awọn Ọlọpa ti sẹ pe, nigbati awọn gbọ ọrọ lẹnu Dokita Shodipọ, ni awọn ba gbe mọto meji ti awọn si gbe Ọgbẹni Omiṣade lọ si ile Dokita Majẹkodun ẹniti iṣe alakoso Ijọba pajawiri Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Nigbati nwọn de ile Dokita Majẹkodunmi, Ọgbẹni Omisade lọ sọ pe on fẹ ri Dokita Majẹkodunmi ti awọn Ọlọpa fi mu lọ.

Ṣugbọn nigbati Ọgbẹni Omiṣade de ile Dokita Majẹkodunmi, o kunlẹ korobata, o si mbẹbẹ lori Orunkun rẹ pe ki Dokita Majẹkodun o le tu on silẹ ninu igbekun.

Lẹhin ti nwọn de ile Dokita Majẹkodunmi, ni Omiṣade ba bẹrẹsi bẹbẹ pe, ki Dokita Majẹkodunmi o le fi on silẹ, gbogbo ohun ti on ba si mọ nipa ọrọ na on yio sọ fun wọn laiku ẹyọ kan lẹhin.



Ọgbẹni Ọdẹsanya



Dokita Majẹkodunmi

Ọgbẹni Ọdẹsanya ni lẹhin ti Omiṣade bẹbẹ tan, ti Dokita Majẹkodunmi si gbọ ohun ti o wi, ni o ba sọ fun un pe, "ọrọ ti o ba wa si ọdọ mi yi ki iṣe ohun ti mo le dasi, lọwọ awọn Ọlọpa ni ọrọ na wa, awọn ni nwọn si le ṣe iranlọwọ fun ọ ki iṣe emi ti o wa wa sile yi."

O ni Ọgbẹni Omisade wa ni ori ikunlẹ ti o nbẹbẹ fun ẹdidi wakati mẹta ki nwọn to kuro nibe ni ọjọ na, awọn Ọlọpa si tun mu pada si ibiti nwọn ti mu wa.

Ṣugbọn ko pẹ pupọ lẹhinna ti ara Omisade ko fi ya, nwọn tun gbe lọ si Ile iwosan, ṣugbọn nigbati o wa ni ile iwosan na ni Ọga Ọlọpanu ba tun lọ ba ni ọhun pe ki o tun ma a rojọ.

WO OJU EWE KẸFA

# OSIKA BA ILẸ KU, ẸNI BA DALẸ A BA'LẸ LỌ

## B'o Ṣe Ogun Ọdun, Ika Yio Ka Onika

OLOTU, Jọwọ gba mi laye ninu iwe rẹ lati sọ itan kekere yi fun gbogbo awọn onkawe rẹ lọmọde lagbalagba, lọkunrin ati lobinrin ki nwọn le ri ẹkọ atata ti o wa ninu iwe na kọ, ki nwọn si ma fi ṣe iwa hu nigbogbo ọjọ aiye wọn, ki nwọn si le ma ranti nigbagbogbo pe ika ko dara ẹniti o da ilẹ dandan ni yio ba ilẹ lọ, ika yio si ba onika bi o ti wulẹ ki asiko pẹ to.

**Lati Ọwọ R. A. Dumoye. Okeya**

Ni akoko kan ti ko ti pẹ pupọ, awọn ọrẹ meji kan wa, ọkan n jẹ Ogundele, ekeji njẹ Adeniyi Ọrẹ awọn mejeji yi pọ to bẹ gẹ ẹ to jẹ wipe, nwọn ko le fi ara wọn silẹ, awọn jọ njẹ, nwọn jọ nmu, ko si ohun ti Ogundele le sọ fun Adeniji, yala otitọ ni o, yala irọ ni o, Adeniji yio gba Ogundele gbọ.

Adeniji ati Ogundele jẹ ọmọ-ọdẹ, ṣugbọn Adeniyi ni owo ọla ati ọla ju Ogundele lọ, ni ẹru ati ẹru, ṣugbọn ika in urẹ si tun juti Ogundele lọ.

Awọn ẹru ati iwọfa ti o wa ni abẹ Adeniji njẹ ọpọlọpọ iya, awọn ti o gba ni osiṣẹ rẹ ko si ni ifọkan balẹ. Ti Ogundele ba le sọfun ki o le ẹnikan lọ, laibere idi rẹ, Adeniji yio le lọ laiberu Olodumare.

Awọn mejeji ko ti lẹ mọ pe Oluwa ju awọn lọ, nwọn hu iwa tani ma mu mi, nwọn si nlo ile aiye wọn laimọ wipe ẹsan yio ke ati pe akukọ yio kọ lẹhin awọn ni ọjọ kan,

O se ni asiko kan awọn ọdẹ fẹ ṣe ajọdun wọn nwọn da ọjọ, olukaluku sise ileri ẹran ti on yio pa fi ṣe ọdun na. Lori eyi, Adeniyi ati Ogundele mura lati wọ igbo lọpa ẹran, nwọn da ọjọ ati lọ.

Nigbati ọjọ pe, Adeniyi gba ọna igbo erin, Ogundele si gba ọna igbo imọdo Awọn mejeji da gberefun ava ati ọmọ wọn nwọn si mu ọna wọn pọn

OGUNDELE DALẸ

Bi nwọn ti fi ilu silẹ ko pẹ na ni olukuluku wọn gba ọna ti rẹ; ki nwọn to ya, nwọn da asiko ati ibi ti awọn yio ti pade.

Ko pẹ na ti nwọn ya tan, Ogundele pada lọsi ile, Ọdalẹ lọ da ilẹ, O lọ ba iyawo Adeniyi, o si baa lo pọ, lo ba pada lọ si igbo Imado,

Bi o ti de igbo yi, o gun Igi kan la ma ṣọ awọn imado ti o ba kọja. O si dẹ pakute si oju ọna ti nwọn ngba kọja,

Ko pẹ pupọ ti imado kan ti o nwa onjẹ fun ọmọ rẹ nkọja lọ. o tẹsẹ bọ pakute, pakute si mu u, O ke igbe lohun rara ṣugbọn bi o ti gbe oju soke, O ri Ogundele pẹlu ibọn rẹ lọwọ rẹ,

Imado yi ni: "Iwọ Ọdẹ, jọwọ da ẹmi mi si, mo ṣẹṣẹ bi ọmọ ni, ọmọ na ni mo si nwa onjẹ lọ fun, Bi o ba fi mi silẹ, ngo ṣe ọ ni ore kan, ṣugbọn ti o ba pa mi, ika yio ka ọ o"

Laiko tilẹ ronu si ohun Imado wi, Ogundele gbe ibọn rẹ, o si yin ibọn ba Imọdo, Imado ke, o yọ ẹsẹ kuro ninu pakute, osi gbọn ara rẹ nu, oni: "Iwọ ika ọdẹ, ti ko si anu ni oju rẹ, o ti nṣe bọ ti pẹ. Wo oke ki o si wo ilẹ, oni ni ọjọ iku rẹ pe."

Were Imado be mọọ, o si pa, o jẹ ninu rẹ o si mu ninu rẹ lọ fun ọmọ rẹ ti ebi ti npa.

Akoko ti nwon da tito. Adeniyi ti de ibi ti nwọn da padepade, oduro duro ko ri Ogundele, o mu ọna igbo Imado pọn, o wa Ogundele lọ. Ko iti rin jin na ti o fi ri oku ọrẹ rẹ ni ilẹ inu rẹ bajẹ, omi si nbọ loju rẹ.

Omura, o lọ sọfun iyawo Ogundele, ariwo ẹkun si ta gee, Enia diẹ lo kanu rẹ nitori iwa kenimani ti on na ti nhu si awọn ara ilu

Ironu wa de ba Adeniji Oronu titi, ṣugbọn ko si oniwa buruku miran bi ti Ogundele, o wa mọ wipe ẹtẹ ati abuku ko jina si on mọ.

O pe iyawo ati ọmọ rẹ o ni, ti o ba di ọjọ ajọdun on o yin ibọn fun ara on, nitoripe Ogundele ko le ku ki on wa laye, O si bẹrẹsi pa ilẹ ile rẹ mọ pẹlu igboya lati yinbọn jẹ.

AṢIRI TU

Nigbati ọjọ ati yinbọn jẹ Adeniyi ku ọla, ọmọ rẹ ọkunrin kan soṣo na ti o bi sare wa si ọdọ Adeniyi, o ni "Baba mi ṣe bi ẹnyin ni ẹ ma nsọ wipe, ẹnikẹni ti o ba da ilẹ a ba ilẹ lọ; lẹhin igbati ẹ lọ si igbo ọdẹ ni ijosi, se bi Ogundele yọ pada lẹhin on pẹlu iya mi si lo pọ.

Ọrọ yi ya Adeniyi lẹnu pupọ, gbogbo ero rẹ lati pa ara rẹ si tuka. O pe iyawo rẹ o si bere ọrọ na, ṣugbọn ọna lati pa irọ ko si fun Obinrin yi.

Laiṣe aniani, Adeniji pe ipade awọn ọdẹ, o sọ fun wọn wipe, ti o ba di ọjọ ajọdun, iyawo on ni awọn yio fi bọ ogun nitoripe o ti da on ati pe on ni o ṣe ku pa Ogundele ọlọrọ on.

Lotitọ nigbati ọjọ pe, nwọn yin ibọn pa iyawo Adeniyi nwọn si fi bọ ogun wọn, Bayi ni Ọdalẹ ọkunrin ati obinrin ba ilẹ lọ.

Adeniyi paapa ko lọ lai jiya, o gbẹsan iwa buruku rẹ ko to lọ laiye. Gbogbo ile ati ọna rẹ ni o ta, nikẹhin o di atọrọ jẹ abẹ bu ka si ni iyara rẹ. O di enia radarada, ẹnikan ko si kanu.

Iwọ osika. itan to fun ọ lati mu ọwọ kuro ninu isẹ buburu. iwa emi ni mo wa nbẹ, ran ti pe ẹnikan loti wa nibẹ iwọ na yio kuro, yio si tun bọ si ẹlomiran lọwọ.

Sikasika ẹ rori nyin wo, ẹ tọrọ aforiji, ki ẹ si ma ṣe rere, ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba mo pe ika ṣiṣe ni iṣẹ,

Ti o ba nṣe, maṣẹ ro wipe Oluwa ko ri ọ, O ri ọ, Ọba onisuru ni , ṣugbọn ko ni fi ẹ si lẹ la ijẹ ẹkun rere iya.

Osika ranti Ọla ẹsan nbẹ.

---


## Congreves Female Remedy

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn Obinrin ti ba ni iyọnu tabi amodi Inu rirun nigbakugba tabu ni ẹkọọkan ẹhin-didun, ibadi-wiwo tabi sisan ẹjẹduda ara tabi aikoto ẹje lara Inu gbigbona nigbakugbi Igba — aiya riru ọmu riro, didun arẹ atinu wa ti oma nfa oyi - oju Ilaogun ara ẹsẹ ara sisọn, ẹfọr abi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itọju gbogbo Obinrin gẹgẹbi Ajo fun ilera ati orişirişi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni inu nigbakugba pẹlu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI JỌ TI WỌN NPE NI:-

## mmoniated Quinine Tincture

Nigba lailai ki awọn Orişirişi rọbirọki egbogi ti wọn ko wa nisisiyi to de awọn agbalagba aiye atijọ mọ aju wipe kosi ohun ti a le fi Iwe egbogi yi bi otutu ikọ iba, orẹrẹ lukuluku onigbameji ti aiperi nyọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio ṣe iwosan rẹ bi danga ni bi oba ti ta diẹ sinu omi ti o lọwọrọ ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itọju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfọ opo-ile-itọ tabi se iwosan iyọnu apo-ile-itọ egbogi aju didun tabi ti ọwa-ọfun didun, ati orişirişi omira pẹlu wọn mbẹ ni ṣọbu awọn :—

Waterloo Medicine Stores,
8, Palm Church Street, Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

# IWE SI OLOTU

## Mo Ki Iyaafin Oloye Awolọwọ

Olotu, Inu mi iba dun ti ẹ ba le gba mi laye lati le ki Iyaafin Oloye H. I. D. Awolọwọ ti iṣe iyawo Baba-salẹ ẹgbẹ Afẹnifẹrẹ fun akitiyan rẹ lẹnu Ọjọ mẹta yi.

Mo kun saara si ọrọ ti osọ ninu ipade awọn obinrin ẹgbẹ Afẹnifẹre ti wọn se ni Mushin la pe yi.

Gidigbi ọrọ jade fun awọn enia alaimọkan lati le fi ru ori wo.

Ọrọ Iyaafin Awolọwọ fi han daju wipe awọn aṣiwaju ẹgbẹ Ọlọmọlagidi ati alatilẹhin wọn nikan lọwọ ibi ipade aiye dern i wọn ṣe ni Ibadan.

Eyiyi fi han daju pe ko si ọrọ hagbagi kan kan fun ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Oduduwa.

Mofẹ ki gbogbo Yoruba mọ daju wipe "Iwaju la o ma lọ ao ni rẹhin lailai.

Maa ba iṣẹ re lọ Iyafin Awolọwọ. Oju ko ni ti ẹ.

Mo dupẹ lọwọ nyin Olotu fun aye ti ẹti gba mi Imọlẹ ti ọjọ kẹtadinlogun osu kerin Ọdun yi, Nitoripe ọrọ ti o sọ o ku diẹ ki o to, ọrọ na ki ṣe otitọ rara.

Emi ni
Bọlari wa Ajala
IBADAN

S. B. dan Alhaji sọ ninu ọrọ re pe awọn fi ọrọ ile-Iwosan lọ Ọba ilu igbaja ko kọ ibi ara si ọrọ na rara, nwọn si gbe ile-iwosan na lọ si Yaru, gbogbo awọn enia ti o ka ọrọ na ninu iwe ni o ya lẹnu lọpọlọpọ.

A bẹ ọrẹ wa S. B. dan Alhaji ki o mọ wadi ohun daju ki o to wa di ododo ibẹ mu dada irọ nla ni dan Alhaji pa mọ awọn enia wa ọrọ na ko ri bẹ rara.

Ko si ojulowo Ọmọ ilu Igbaja ki o gbọ ọrọ na, nibiti ọrẹ wa ti gbọ tirẹ sa nya wa lẹnu ni, ko yẹ ki a mọ da edeaiyede silẹ larin ilu wa ati ilu miran pẹlu.

Irẹpọ ni a nwa ilu wa, a ko fẹ ija rara ẹ jẹ ki a ni fẹ nla si ara wa.

Mo dupẹ pupọ fun aye ti ẹ gba mi, Ọkọ Ọba ko ni sa nyin lẹsẹ o.

Emi ni
ASANI AJIBỌDE
Igbaja.

## Mo Gba Fun Bakare

Inu mi yio dun pupọ bi Olotu ba le gba mi ni aye die ni nu iwe rẹ arimọlelọ, awo pọbla da, iwe aladun ti nfi ọna idera han wa lati dupẹ lọwọ Ogbẹni R. A. Bakare fun ọrọ re to ojade ninu iwe Irohin Imọlẹ ninu oṣu yi nigbati o kesi gbogbo awọn ọmọ Omupo pe ki nwọn ni ẹgbẹkan ṣoṣo.

Mo faramọ imọran na fun idagbasoke ilu wa, nitoripe nini ẹgbe ọmọ ilu kan ṣoṣo ntabuku ilu wa. Bẹni ilu ko kere ni nu ile Igbomina Bẹna ni A. K. Ẹdakolaropin nṣe wahala ki ilu wa le ni ilọsiwaju Ọlọrun yio ran ọ lọwọ.

Awọn ilu ti ko to Omupo lo ni ẹgbe Ibilẹ kan ti gbogbo awọn ọmọ wa ninu re, ilu wọn lẹ ni ilọsiwaju bi ti ilu toku.

Ẹjẹ ki ari ọrọ wi siwaju awọn agbalagba ki nwọn ran wa lọwọ lati le ni ẹgbe ibilẹ kan, ki gbo gbo wa da imọran pọ, ki a wa dari.

Ki gbogbo ẹgbẹ to wa ninu ilu Omupo pa ara wọn pọ laika ẹgbe ti ẹnikọọkan wa, ẹgbe yi

ni yio tun ilu wa se ti nwọn yio si le mo wa alafia ilu wa

Olotu aṣiri nyin ni tu o.

Emi ni,
Lasisi
EKO

## Esi Ọrọ Ọrẹlaja

Olotu, ẹ dakun ẹ gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin oloyinmọmọ ti njade lojojumọ ti o si nkọ wa ni ọgbọn ati oye lati fesi si ọrọ Omidan Celinah Ọrẹlaja ti o jade ninu iwe nyin ti ọjọ kọkanlelogun oṣu kẹrin ọdun yi.

O bere wipe ninu ọmọ mẹfẹfa ti baba na bi ti onikaluku si mu imọran wa lori lile ti onile ti nwọn ngbe fẹ le wọn jade fun gbe se owo ile ti nwọn jẹ.

Ọmọ kini ni ki awọn lọ gba ile miran, ekeji ni ki awọn pada sile, ẹkẹta ni ki awọn ma jade kuro ninu ile na, ẹkẹrin ni ki awọn lọ ko ti awọn ẹkarun ni ki nwọn lọ gbe ibiti awọn ba ri ati ẹkẹfa sọ pe, ki awọn kuku fi ogun pa onile na.

Idahun temi ni wipe ti ẹnikeji ni o yẹ ki baba na gbagbọ nitoripe bi nwọn lọ kọ ile miran ẹni ti ko ri owo ile san ko le ri owo kọle, bẹna ni bi nwọn lọ wa ile miran lati ma gbe, owo ile sisan tun nkọ? Bi nwọn ṣe oogun pa onile na, ogun rẹ ko le kan wọn lailai.

Bi iwaju ko ba ṣe lọ, ẹhin a ṣe pada si, ki nwọn pada sẹhin ki nwọn lọ si ilu wọn lo dara ju.

Mo dupẹ aye ti ẹ gba mi ajinde ara yio ma jẹ o.

Emi ni,
E. A. Ogundokun
Oro-Offa.

## Dan Alhaji Parọ

Inu mi yio dun pupọ ti olotu ba le gba mi ni aye diẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ ti njade lojojumọ lati si ọrọ Ọgbẹni S. B. Dan Alhaji ti o jade ninu iwe Irohin


## Ibọosi Ikọ Ti Ọjọ Rẹ Ti Pẹ Lara

Pupọ ninu awọn egbogi rọbirọbi ti wọn npolowo ti wọn si nta kakia igoroiju Eko ati ni igbereko ko ni ṣe iwsan wọn lailai afi ki o ri ojulowo haunhaun atanmase egbogi ti o lagbara gidigidi ti o le ṣe iwosan rẹ tit de inu ifun ati igb-aya ti yio mu ọ ma tu "Ikọ" mọ ni kẹlẹbẹ jade ti o ba nhu ẹ titi yio fi tan ni inu rẹ qatabata. Awọn ikọ miran wa ti o dabi ẹnipe wọn ama la ogun tabi orişirişi egbogi tabi ti o ba jẹ pe bẹni, agba ọ ni imọran wipe ki o ma lo egbogi awọn ara ilu Abyssinia ti nwọn npe ni "Etibard" pẹlu egbogi ti o ba amu

PORAL TABLETS
THIOLYPTINE SYRUP
THYMO-EPHDRIN LINITUSS
ETIBARD ABYSSINIA POWDER

Fun iwosan ikọ Asima, ikọ fere ikọ otutu igba-aiya ikọ gbẹdu, ikọ-ọnafun, ikọ-gbigbẹ tabi eyiti o ma nmu ki enia ma ha ọna-ọfun tabi pẹlu kẹlẹbẹ tabi ti o ma njẹ ki nia ru nipa wahala tabi aikoni le sun daradara lọsana ati loru-gbiyanu lati dan ọkan ninu awọn egbogi alagbara idigidi wọnyi wo fun ara rẹ iwọ yio si ri iyatọ gburugburu larin wọn si awọn olomi ṣorokiti ti wọn nta kakiri

O daju nibẹ iwọ yio bẹrẹ si ri alafia, iwọ yio ma ṣun daradara wasi ma sun fọnfọn pẹlu Alafia de si ọ ni yẹn Iṣe egbogi ajẹbina y ni sọbu awọn:—

Waterloo Medicine Store
8 Plamchurch Street, Lagos
Phone:-22878 ,Nigeria, (Ọja ita Faji)



## Iwọ Ha Nlọ Si Mẹkka Ni Ọdun Ti nbọ Bi?

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA"
MO JẸ RI O, OLUWA MO JẸ IPE RẸ
ẹnikẹni ti o ba fẹ lọ si "MẸKKA" Ilu Mimọ ni ọdun yi gbọdọ ni iwe

"AFINIMỌNA NPA ISIN HAJI"
LỌWỌ KI OLUWARẸ MA BA ŞINA TABI NA OWO INAKUNA. KI O LE LỌ ALỌBỌ MẸKKA NA DADA
t'Oluwa jọwọ ṣe Isin Haji wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ fun wa ni rere ti aiye ati t'ọrun Oluwa wa, ki o sisọ wa ni bi iya nitori IWỌ NI ỌBA alagbara Olubor gbogbo ẹda patapata" Amin

### "WAS SALAM"

*AKIYESI* Gbogbo Musulumi Ododo ti oye ki o ri na lọwọ nitori igbati yio ba fẹ lọ si MẸKKA
*Iye Owo 5/6, £3 fun dosini*

MANAGER
N2/99 SHITTU STREET
Ibadan



## Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ni ọjọ kẹta oşu karun (3/5/64) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Bamgbose Street Eko.

Ao si tun fi tayọtayọ gba awọn ọmọ ẹgbẹ titun ti nwọn ba wa si ipade lati jẹ ọmọ ẹgbẹ.

Ki ẹ tete de o.

LATIFU BABALỌLA
Adele Akọwe

# Itumọ Ala

J. O. Daramọla Kano:- Ṣọra lati rin irinajo loju omi lasekoyi, ki o ma ba ba wọn wọ awọku iku omi.
Fesitan Afọlabi Ikereku Abẹokuta:- Ṣọra nipa akowaba ati adawaba, ki ọrọ ọlọrọ ma ba di tirẹ.
Chrristopner Aderibigbe Itirẹ:- Iwọ yio gbọ iro rere kan lati ilu okere ti yio ṣe ọ ni anfani.
Festus Fakorede Ibadan:- Ijatilẹ yio ba ọ lairotẹlẹ maṣe banujẹ abọsilẹ rẹ rere ni yio jasi.
Lalonpe Ayọka Mushin - Awọn ẹni ibi aiye ni o ngbogun ti ọ loju orun lati ṣe ọ ni jamba kun fun adura ki ọwọ ma ba tẹ ọ.
Ogunnaike Osidipẹ Sagamu - Anikun owo, ọmọ ati alafia ara ni itumọ ala na

AKIYESI

Iranlọwọ ni eyi jẹ fun ọ ti o ba la ala, maṣe jafara lati kọwe bere itumọ rẹ lọwọ mi ni ọfẹ, nitoripe ala pin si meji rere ati buburu. Ẹnikẹni ti o ba la ala ti ko ba si mọ itumọ rẹ wa lọwọ ewu.
Kọwe bere itumọ ala rẹ lọwọ Josefu Alala itumọ rẹ yio si jade ninu iwe Imọlẹ.

Josẹfu Alala
1, Isiba Street, Itirẹ via Yaba
c/o Postal Agent Itirẹ

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 21 - Feb 19) Iwọ yio gbọ irohin amodi ọmọde kekere kan, maṣe barajẹ nipa rẹ ko si kini kan. Iwọ yio si tun ri iwe kan gba nipa iṣẹ ti o yẹ ki o ṣe.

PISCES (Feb 20 - Mar 20) Iwọ yio ri pe yio ṣoro fun ọ lati pe ni omugo, ọjọrọ ọjọ oni yio ladun yio loyin fun ọ.

ARIES (Mar 21 - April 20) Iwọ yio lọ si ibiti o jina loni, Ija kan ti o ti wa nilẹ yio pari lọna iyanu.

TAURUS (April 21–May 22) Sure fun awọn ti o nfi o ṣepe, tun ara ati ọkan rẹ ṣe, masi ṣe lọ si eti odo Iṣọra ni pataki ẹbọ

GEMINI (May 23– June 21) Iṣoro yio wa fun ọ loni, maṣe ko ẹgbẹ buruku, nṣe ni ko mu suru, gbogbo ohun ti o ti sokunkun fun ọ ni yio han kedere

CANCER (June 22–July 23) Ṣọra nitori awọn ajẹni lẹhin ki nwọn maṣe ba orukọ rẹ jẹ. Ijaka le bẹ silẹ larin iwọ ati ẹlẹgbẹ rẹ. Ṣọ ọrọ to ma bọ lẹnu rẹ, ki o si mọ ede ti iwọ yio pe.

LEO (July 24–Aug 22) Mase binu pupọ pẹlu awọn Ọmọ abẹ rẹ Inu rere rẹ le gbe ọ lọ si idalẹ sọra maṣe jẹki nwọn ji ọ gbe loni ohun kan ti o ngbero dara, ṣugbọn maṣe ju ara rẹ lọ.

VIRGO (Aug 22–Sept 23) Ohun kan ti o ngbero lati ṣe yio suwọn Ija kan ti o mbẹ larin iwọ pẹlu ọrẹ rẹ kan, yio pari Arisiki yio de si ọ laipẹ.

LIBRA (Sept 24 - Oct 23) Idilọwọ yio wa fun arisiki rẹ loni Iṣẹ ọna tabi aworan yiya yio dara fun ọ pupọ loni.

SCORPIO (Oct. 24–Nov. 22) Itẹlọrun yio wa fun ọ ninu ile rẹ ija ti o wa nilẹ ti fo lọ, ṣọra rẹ nigbogbo ọjọ oni, ki iru nkan bawọnni maṣe ṣẹlẹ.

SAGITTARUS (Nov. 23–Dec. 22.) Lakaye ati ọgbọn ori rẹ ni iwọ yio fi bori idanwo ti o ti nda ọ lamu. mu ọkan duro iwọ o si ri ire. Orun ni kio sun loni ki re ara tẹ.

CAPRICORN (Dec. 23–Jan.) Iwọ yio lo ọla aye kan lati fi pari ọrọ kan, ire nla kan mbẹ fun ọ ni owurọ yi.

BI O BA NI

**Iwe—Titẹ**

FUN

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orisirisi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe Igbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ ẸRỌ—ITẸWE
**Modupẹ Printing Press**
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.
KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
*OWO PỌKU NI A SI NGBA*

IROHIN KO TO AFOJUBA
*Dan wa wo lẹẹkanṣoṣo ki o si ri iyatọ*

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARASEN TI NWỌN NPE NI- Eleyi yatọ patapata si awọn

**RICHALET**

Rọbi-rọbi. Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA' bi Mọna mọnọ

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO




Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nti kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyẹn ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni lẹ yi,

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba wọn yẹn a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Iatambulu si Itali jẹ

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le ṣe ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun. Jẹdijẹdi Akọba, arun Ẹdọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa Egbogi-Amodi Apo ile ilọ, ẹhin didun tabi ibaradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa nba ẹjẹ ara rẹ patapata yio si ni ẹjẹ rẹ mọ toritoni pẹlu.

Ṣa dan igo rẹ ka o iwọ yio si ma a rohin rẹ fun mi-na pẹlu

Bere ni Ṣọbu awọn:—

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street ( Lagos.
Phone: 22858 Nigeria, Ọja Ita Faji)

Adedun Chemist
14, Wakeman Street, Yaba

Ati ni awọn ẹ Iba:-
Iṣẹ Olodumare Dipensary Oke-Bọla

# Ẹgbẹ N. P. C. Ja Ẹgbẹ N. N. D. P. Kulẹ!

Irohin de eti wa lati ẹnu ọkan ninu awọn olori ẹgbẹ N. P. C. pe ajumọṣepọ ti ẹgbẹ Akintọla Dẹmọ (N N. D. P.) fẹ ba ẹgbẹ wọn ṣe ko bẹsi rara ati pe awọn ọmọ ẹgbẹ na si kọ delẹ lati ba awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ṣepọ.

Ninu ọrọ ti awọn ẹgbẹ N. P C. sọ fun onirohin wa wipe ajumọṣepọ wọn ko le waiye rara ati pe ọpọlọpọ ninu awọn to jẹ olori ninu ẹgbẹ na lo ti da ẹgbẹ ti wọn ti nṣe tẹlẹ ati pe ọpọlọpọ awọn to wa ninu ẹgbẹ na ti o ti jẹ ọmọ ẹgbẹAlakukọ N C N C tẹlẹ ti wọn si da ẹgbẹ na, ati pe ẹgbẹ ti wọn ti wa tẹlẹ na ni o si ti gbe wọn si ipo ti wọn wa tẹlẹ ki nwọn to yi wọn po

Awọn ọmọ ẹgbẹ NPC si tun sọ si i pe o san ki awọn wa pẹlu ẹgbẹ N. C. N.C. ti awọn ti jijọ nṣe ajumọṣepọ lati ẹhin ju pe ki nwọn ba awọn ẹgbẹ ti ko daloju pe igbẹhin ẹgbẹ na le dara tabi ti awọn ọpọlọpọ enia Ipinlẹ ko iti mọ rara.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na si tun fi ye onirohin wa lati bi oṣu meje ti nwọn ti da ẹgbẹ N.N.D.P. silẹ ni wọn ti nlọ si Kaduna ni Ipinlẹ Ariwa lati lọ ṣe eto bi ajumọṣepọ na yio ṣe bọ si ṣugbọn gbogbo rẹ si ja si asan

Ọpọlọpọ ipade ni awọn ọmọ ẹgbẹ meji na si ti ṣe pọ fun eto ajumọṣepọ awọn ọmọ ẹgbẹ N. N. D. P. ati pe ọpọlọpọ ibere ni awọn ọmọ ẹgbẹ NPC ti bere lọwọ nwọn nipa ti eto ipade na ṣugbọn awọn ọmọ ẹgbẹ NPC si kọ delẹ fun awọn Olori ẹgbẹ Dẹmọ ṣugbọn awọn ẹgbẹ NPC si sọ fun nwọn pe nwọn yio tun ṣe ipade miran nipa eto ipade ajumọṣepọ na nigbati o ba ya.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na si tun sọ pe nkan ti ko ni jẹ ki nwọn ba awọn ẹgbẹ NNDP ṣe pọ ni pe.

Ọpọlọpọ awọn enia ti ko ni igbẹkẹle rara ati pe ko si ẹni to le mọ otitọ inu wọn.

Ati pe awọn ọmọ ẹgbẹ N N D P kan na yio hu iwa ọdalẹ si awọn ẹgbẹ N. P. C. to ba ya.

Ti ko ba jẹ nkan to ṣẹlẹ lori ọrọ ikania to ṣẹlẹ ati pe awọn si fẹ ẹgbẹ NCNC ti o jẹ alabaṣepọ wọn ninu ijọba Apapọ ati pe awọn si ni igbẹkẹle ninu wọn ati pe wọn si jẹ olotitọ ju ẹgbẹ N.N.D.P lọ.

Ati pe ajumọṣepọ ẹgbẹ N.N.D.P. pẹlu ẹgbẹ N.P.C. yio mu ki awọn enia ma ni fẹran awọn ati pe yio mu ki ẹgbẹ N. P. C. ma gbajumọ mọ.

Igbẹhin ẹgbẹ NNDP ki iṣe nkan ti yio ni igbẹkẹle na rara ati pe ẹgbẹ na ko ti lọ fun idibo lati lọ dan ara nwọn wo boya awọn enia tẹ nwọn tabi nwọn ko fẹ nwọn.

Awọn ọmọ ẹgbẹ NNDP si tun nṣe agbara bi nwọn yio ṣe tun ṣe eto bi nwọn yio ṣe bi ajumọṣepọ nwọn pẹlu NPC. Gẹgẹbi eto awọn ọmọ NNDP yio ṣe bẹsi fun ajumọṣepọ na, nwọn si ti yan ninu awọn olori ọmọ ẹgbẹ NPC Ọlọla Ahmadu Bello ti o de lati Mẹkka nijẹta yi lati lọ fun eto ajumọṣepọ na.

## IDAKẸ JẸJẸ

Awọn ẹgbẹ NNDP si ngbero lati wọ ajumọṣepọ pẹlu NPC ki nwọn le ri aye wọ Ijọba Apapa ilẹ Naijiria, Awọn ọmọ ẹgbẹ NNDP si tun ro pe ti wọn ba le wọ Ijọba Apapa yio tun fun nwọn laye lati le wọle idibo Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria,

Awọn ọmọ ẹgbẹ NPC si tun fi ye onirohin wa pe awọn NNDP ko si ni sọ nkankan nipa ọrọ eto ajumọṣepọ ti awọn ọmọ ẹgbẹ NPC si fi ja nwọn tule.

Nwọn tun fun onirohin wa pe rogbodiya kan si wa larin igbakeji Olotu Ipinlẹ Iwọ Orun Oloye Rẹmi Fani-Kayọde ati Ọba C. D. Akran nipa ẹniti oni agbara ju ninu ẹgbẹ N N D P ati pe rogbodiyan na si nju bẹ titi di isiyin

Nwọn tun fi ye o rohin wa Oloye FaniKayọde si ti nrẹlẹ ninu ẹgbẹ Dẹmọ sugbọn ọba C. D, Akaran si ngba agbara si, lati ẹgbẹ Dẹmọ ati pe ọpọlọpọ awọn gbajumọ ẹgbẹ na lo si fi ara mọ Ọba Akran.

Oloye S. L. Akintọla olotu Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria, pupọ ninu awọn Minista ipinlẹ iwọ orun ati apapọ awọn olori ẹgbẹ N N D P. lo si fara-mọ Ọba Akran ati pe oloye Fani-Kayọde yio fori balẹ laipẹ yi

# IWE ITUMỌ ALA

Josẹfu Alala ti ẹ ti nkan ninu iwe Irohin Yoruba ti jade ni odindi fun tita nisisiyi.

OHUN TI O WA NINU IWE NA

1. Egbogi Ajẹbidan agbabiẹtu.
2. Odu Ifa mẹrindinlogun lati ma a fi yẹ itumọ ala rẹ wo.
3. Ẹnikẹni ti o ba ra iwe yi ni anfani lati bere ala rẹ nigba gbogbo lọfẹ lọwọ Josefu Alala.
4. Koiti si ikeji rẹ ninu iwe itumọ ala ti o ti njade ri nitoripe JOSẸFU ALALA ni o ṣe e

Tete ra tirẹ loni ki o to tan.

AKIYESI

A tun nfẹ asoju ti yio ma ba wa ta iwe na, owo pọọku ni ao ta fun wọn ki nwọn ba ri ere gọbọi jẹ ti o ba fẹ se asoju wa kọwe fun iwe adehun,

Iye owo 5/- £2

**J. O. Shoyinka**
N2/99 Shittu Street
Ibadan

tabi

1, Isiba Street Odo Ẹran
c/o Postal Agent
Itirẹ Suru—Lere, Lagos.

# E ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ

# EGBOGI JẸDIJẸDI

BERE EGBOGI



## "CYCLOVEN"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara rẹ si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi Iho idi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnsẹ. Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri lode nisiyi ti wọn a ma po owo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la leri mẹwa ninu ọgọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lẹ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara, Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakana. Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa aiko mẹ ṣe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ, ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pẹlu lojoujmọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Ṣuga tabi oniruru ohun adidun pupọju nigbakugba, Jẹdijẹdi orişirişi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ ade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnsẹ, tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnṣẹ tan ni, tabi ti nrin ọ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egboogi "CYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani ṣẹṣẹ wa idi rẹ ki o si danwo orişi meta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alafia yio de si ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogid taa igboro ilu Naijiria jakejado, Bere rẹ ni:

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)

# IROHIN IMOLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 592 WEDNESDAY, APRIL 29, 1964 (2D)


## Ọkunrin Kan Ji Lawani Gbe

KANO:— Oju gba gbogbo enia ti fun Ọdọmọdekunrin kan, Hassan Ishiaku, eni Ogbọn Ọdun, ti awọn Ọlọpa sọ pe ko ni ibugbe kan, ni awọn Ọlọpa mu wa siwaju Adajọ Agba Ile ẹjọ kekere Kano ni Ọjọ Aje ti iṣe Ọjọ kẹtadinlọgbọn Oṣu kẹrin Ọdun yi fun ẹṣun ole jija.

Ọlọpa ti o ba Ọdaran na ṣejọ ṣe alaye fun Ile-ẹjọ pe, Ọdaran na jẹ Ọkan ninu awọn Oṣiṣẹ ile iṣẹ "John Holt" ni Kano.

Ṣugbọn Ọdaran na gba ọna alumakọroyin o si awọn awọ ewure ti awọn Oyinbo Onişowo na nta gbe ti iye owo rẹ jẹ pọnun mẹrinla (£14) gbe.

Siwaju eyi ni, nwọn ti nba Ọdaran na ṣejọ pe o ji ẹwu agbada ati lawani Malam Abdul Musa gbe nigbati o lọ wo Ọkunrin na nibi iṣẹ alẹ ti Malam na nṣe labẹ "John Holt" ti awọn mejeji gbe nṣiṣẹ ni Ọjọ Ẹti ti iṣe Ọjọ kẹtadinlogun Oṣu yi.

Onirohin wa fi ye wa pe, nigbati nwọn nle Ọdaran na nibiti o gbe lọ jale, o subu o si fi ara gba Ọgbẹ, pelu ọgbẹ na ni awọn Ọlọpa mu wa si Ile-ẹjọ ti awọn Dọkita si di i fun.

Nigbati Ọdaran na rojọ, ti o si gba wipe en jẹbi, ni adajọ ba ni ki o lọ fi ẹwọn Ọdun meji jura.

## Ijẹsha Kilọ Fun Ẹgbẹ Dẹmọ

# "Ẹ MAṢE FITINA AWỌN ENIA WA MỌ"

ILESHA:- Ni ọjọ Aiku ti ise ọjọ kẹrindinlọgbọn oṣu yi ni gbogbo awọn ọmọ Ijẹsha nile ati ni oko pejọpọ ti nwọn si ṣe ipade gbangba ode kan, labẹ alaga, Oloye M. A. Ajayi-Obe, alaga Igbimọ Ijọba Ibilẹ Ilesha ati ọkan ninu awọn ọmọ ile Igbimọ Agba oṣelu fun Apapọ Ijọba Naijiria lori gbogbo bi nkan ti ṣe nlọ ni Ijẹsha nisisiyi.

Irohin fi ye wa pe, gbogbo awọn oloye ati awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu pẹlu awọn enia sarakisaraki ilu ni nwọn ṣe ipade na, ṣugbọn awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Alakukọ lọ pọ ninu ipade na.

Alaga ipade na Oloye M. A. Ajayi-Obe se alaye pe, ohun ti o fa ti on fi pe ipade na ni rogbodiyan ti o ṣelẹ ninu ilu na nigbati oloye S. L. Akintọla olori ẹgbẹ Dẹmọ ati oloye Fani-Kayọde ti iṣe igbakeji rẹ ṣe ibẹwo wa si ilu na laipẹ.

Lẹhinti ọpọlọpọ enia ti sọrọ lori ọrọ na tan, ni Ọgbẹni S. O. Thompson, ọkan ninu awọn asiwaju ẹgbẹ Afẹnifẹre wa dide sọrọ,

Ninu ọrọ rẹ, Ọgbẹni Thompson pe, ija ti o ṣelẹ ni ọjọ na ki iṣe lasan ni ija na ṣelẹ.

Ọgbẹni Tompson ṣe alaye pe, nigbati awọn enia na ti mbọ ni awọn ti ngbọ irohin ni abẹlẹ pe, "Tulasi bi a fẹ bi ako fẹ, a gbọdọ gba ẹgbẹ Dẹmọ ni, ati pe awọn enia na yio ba ile Ọgbẹni Lawrence Ọmọle jẹ, ẹniti iṣe ọmọ ẹgbẹ A. G. ati ile iṣẹ awọ ọmọ ẹgbẹ N. C. N. C. jẹ nigba ti nwọn bade"

O ni ko si ohun ti awọn le ṣe ju pe, "ki a mura silẹ de ohun ti o ba mbọ wa ṣe wa ninu ile wa lọ"

Ni ipari ọrọ ti o sọ ki ipade ọjọ na to tuka, gbo gbo enia lo ho gee, nigba ti Ọgbẹni Tompson sọ pe "Awọn enia ti o ba nwa enia kun ara wọn ki iṣe pẹlu halẹ lati mu enia ṣe ti wọn ni nwọn o fi ṣe"

O wa pari ọrọ rẹ bayi pe "ki ẹnikẹni o maṣe wa fitina awọn enia wa mọ, ohun ti a ba sọ pe a ko fẹ, ko si oluwarẹ ti o le fipa mu wa.

# 'Ọlọpa Dẹruba Omiṣade'

AKETE AISAN

Ṣugbọn nigbati oga Ọlọpa, Ọgbẹni John Lynn de ọdọ Ọgbẹni Omiṣade ninu ile iwosan na, Omiṣade sọ fun wọn pe. on ko ni alafia nitoripe, ara on ko ya, on ko si le ro ẹjọ kankan lori akete aisan.

Ọgbẹni Ọdẹsanya sọ pẹlu iyanu pe, o ya ẹnikẹni lenu pe adajọ ko se akiyesi pe, pẹlu ihalẹ ati ibẹru ni awọn Ọlọpa fi mu Omiṣade rojọ, nigbati nwọn mu de Tesan.

O tun ṣe alaye pe. nigbati ẹnikan ba wa ninu iyọnu ko si Ohun ti Oluwarẹ ko le ṣe, o le purọ lati fi bọ kuro ninu iyọnu, paapajulọ ẹni nwọn fi Ofin pajawiri gbe.

Gbogbo ile ẹjọ lo bu si ẹrin ti nwọn si rẹrin arin takiti nigbati Ọdẹsanya sọ pe "Bi Ọrọ na ti ṣe lọ ni mo sọ yi, ṣugbọn nwọn ko fi Ofin pajawiri gbe mi ri ko jẹki ngmọ ju bayi lọ."

Ṣugbọn Ọdẹsanya ko ti pari ọrọ rẹ ti Ọlọla Adetokun Ademọla fi sọ fun un pe, "Ṣe bi, Omiṣade ti sọ fun ile ẹjọ pe on ko sọ bẹ kini ṣe ti o ko sọrọ gan an lori ẹjọ ti Omisade ro, ti o si gba pe bẹni on sọ?"

Ọdẹsanya "Bẹni Oluwa mi, awọn ọlọpa ti kuna lati ṣe iṣe wọn lọna ẹtọ"

Lẹsẹkẹsẹ ni ọgbẹni Ọdẹsanya mu iwe idajọ kan jade ti o si ka iwe na ki ile ẹjọ o le ba gba pẹlu on pe awọn ọloka kuna lati ṣe iṣẹ wọn lọna ti o yẹ.

Adetokunbọ "kini iyẹn ni ṣe pẹlu ẹjọ ti o wa nilẹ yi? Ohun ti o le sọrọ le lori ni pe, Omisade wa ni abẹ ofin pajawiri nigbana ki o si fi ọrọ miran gbe ọrọ rẹ lẹsẹ lati inu iwe ẹjọ" Ọdẹsanya: "Mo dupẹ Oluwa mi Omi lo pọ ju gari lọ"

Ṣubọn bi Ọgbẹni Ọdẹsanya ti ṣe dupẹ tan lọwọ adajọ agba, ti o si nsọrọ lori bi awọn Ọlọpa ti ṣe fi ofin pajawiri gbe, ati bi Ọgbẹni Lynn ti ṣe sọ pe on bere ọrọ lọwọ Omiṣade nigbati on (John Lynn) si kọ ọrọ na silẹ tan, Omiṣade kọ la ti kọwọ bọ iwe na.

Bi o ti nsọrọ yi lọwọ ni Ọlọla Louis Mbanefo wa bere lọwọ rẹ pe, "Ọgbẹni Ọdẹsanya, kini ṣe ti o ko le sọ fun wa, ọna ti o sọ pe adajọ gba ti o fi ṣi ara rẹ lọna ki o si fi gbogbo eyi ti o nwi yi silẹ diẹ na ?"

Ọgbẹni Ọdẹsanya dupẹ lọwọ Ọlọla Mbanefo fun imọran ti o gba a. Lẹhinna ni o wa ṣe alaye lori ọna pataki meji ti adajọ ṣe ṣi ara rẹ lọna.

Bi o ti nsọro rẹ lọwọ ni o ba pe akiyesi awọn adajọ si oju ewe kejidinlogun (page 18) ẹda iwe idajọ ti adajọ da ni ile ẹjọ ni ọdun ti o kọja yi.

Bi o ti nsọ rẹ lọ ni ni Ọgbẹni Vahe Briramia nsọ pe, "kini adajọ ṣe to sọ pe o lodi si ofin"

Bi Ọgbẹn Ọdẹsanya ti fẹ ma a ṣe alaye ni Ọlọla Adetokunbọ sọ fun un pe, " ka ọrọ na fun wa ninu iwe ki a le mọ pe nitotọ ni"

Ọrọ yi gba Ọgbẹni Ọdẹsanya to iṣẹju marun ti o ti o nfi nwa inu iwe idajọ ti ko si ri, ṣugbọn lẹsẹkẹsẹ ni Ọlọla Adetokuobọ sọ ibiti ọrọ na wa fun un.

Adetokunbọ:- "Wo oju ewe kẹrinlelọgbọn (page 34) gbogbo ohun ti o le ran ọ lọwọ ninu ọrọ rẹ lo wa nibẹ"

Ọdẹsanya: "Mo dupẹ pupọ, Oluwa mi"

Ninu Ọrọ na ni awọn Ọlọpa ti halẹ si Omiṣade pe ti o ba le sọ otitọ awọn yio da abo bo, ti kini kan kosi ni le se ti ẹjọ na bade kotu.

Ọgbẹni Ọdẹsanya ti pari Ọrọ rẹ, Ọgbẹni Kellock agbẹjọro Oyinbo ti yio ṣe ẹjọ Ọlawọyin ati Onitiri bẹrẹsi sọrọ yio si tun ma a ba Ọrọ rẹ lọ ni Owurọ yi.


Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M. S. Grammar School) Bariga 29/4/64